**Ọrọ agba**

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbaje. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

# Irohin Yoruba

NO 124 WEDNESDAY OCTOBER 28—TUESDAY NOVEMBER 3 1964 KOBO MẸTA 3D

**Akiyesi**

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

# IPADE 'UPGA' BUAYA



'Irohin Yoruba' tun gbe de, awọn aworan awomalẹlọ ati awokawọkọ fun Ẹgbẹ Onikumọ. Aworan oke eti ti isalẹ yi fi apakan ọkẹ aimoye enia ti o wa si ipade ba gbangba 'UPGA' ni ọjọ Abamẹta ni Ibadan han. Awọn aworan na sọ itan ara wọn.



## 'Ẹgbẹ Onikumọ fẹ lu jibiti'

Bi awọn ọkunrin, lẹmọde ati lagba ti pọ jantirẹrẹ bi eṣu ni awọn obinrin, lọmọde ati lagba pọ bi ewe rumọ. Ẹgan ni hẹ! Awọn enia ko lonka nibi ipade ipolowo idibo awọn ẹgbẹ Itẹsiwaju UPGA (Ọlọpẹ, Alakukọ ati Onirawọ) ti o bẹrẹ ni papa iṣere Race Course ni Ibadan ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kerinlelogun oṣu yi. Oju ko iti ri iru ọpọ enia bẹ ri ninu itan ipade ita gbangba iṣelu ni Ibadan. O koyẹyọ.

Lati agogo mọkanla owurọ ọjọ na ni awọn enia ni ẹgbẹgbẹrun ti nya wọ papa iṣere na.

Ni abule Aba-nla ti o to ibusọ mẹdogun si Ibadan ni ogunlọgọ enia ti lọ pade Olotu Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ati olori ẹgbẹ Alakukọ, Dokita Michael Okpara ati awọn ogunna gbongbo ẹgbẹ Itẹsiwaju UPGA.

Pẹlu ijo ati orin apọnle aladun ni awọn enia ilu Ibadan fi pade awọn aṣiwaju ẹgbẹ UPGA na. Bi ilu ti ndun, ni orin nsọ lọtun losi oju titi, ti igbe Awo! Awo!!, Zik! Zik!!, M.I. Power njade lati ẹnu ẹgbaagbeje enia lakọlakọ. Oju titi ti lọlu nigbati Dokita Okpara fi ma de ile Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni Oke Ado pẹlu ẹgbẹgbẹrun enia ti o mu imọ ọpẹ ti iṣe ami ẹgbẹ Ọlọpẹ lọwọ. Fun ọpọlọpọ wakati ni awọn mọto ko le fi lọ siwaju ati si ẹhin.

Alhaji D. S. Adegbenro, babasalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre, Oloye (Iyaafin) Hannah Awolọwọ, Ọgbẹni J. A. Ọdẹku, Oloye J. A. O. Odẹbiyi, Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ ati Oloye Akin Olugbade wa ninu awọn aṣiwaju ẹgbẹ Ọlọpẹ ti o gba Dokita Okpara ni alejo si ile Oloye Awolọwọ.

Ko pẹ pupọ lẹhin ti Dokita Okpara wọ ile Oloye Awolọwọ tan ni gbogbo awọn aṣiwaju na ba fijo tayọ lọ si papa iṣere Race Course. Akoko na to agogo mẹrin ati abọ irọlẹ.

Ninu ọrọ ti o ba awọn enia na sọ, Dokita

(Wo oju ewe kẹjọ)




## Igi da mọ Dọmọnu lori

Ọrọ ẹgbẹ Domonu (NNDP) ni Ipinle Iwọ Orun ti di ile ti a fi ito mọ ti o je pa iri ni iwo palẹ' aitoripe igi ti bere si da mo egbe na lori lọkọkan nisisiyi.

Okan ninu ajalu ibi nlanla ti o jalu egbe na ni ọjọ Aje ti ise ogunjọ osu yi ni pe ọkan ninu ogunnagbongbo awon Alakoso ijoba egbe na, Ọgbẹni J Olu Jones Omokowajọ ti fi egbe na silẹ patapata, o si ti yowoyọtẹ ninu ẹgbẹ na, ati Igbimọ Alabẹsekele Ijoba Akintola.

Ọgbẹni Jones Omokowajo je Alakoso ijoba fun eto Iṣẹ agbe ni Ipinlẹ Iwọ Orun, sugbon o ti fi ipo yi na sile bakanna.

Iwe ni Ọgbẹni Omokowajo ti iṣe asoju Ariwa Iwọ Orun Okitipupa ko si Oloye S. L. Akintola ti iṣe babasalẹ egbe Domonu lati so ipinnu rẹ na fun un ni ojo na.

Ijamba mọto ayokẹlẹ se Ọgbẹni Omokowajo ni osu keji ọdun yi, o si wa ni ile iwosan titi o fi di ogunjọ osu yi ti nwon di sile ni ile iwosan na.

Ese kan aiye, ese kan orun ni Ọgbẹni Omokowajo wa fun odidi osu kan ti o de ile iwosan na.

Ninu iwe na ti o ko si Oloye Akintola, o tu asiri pe ile iwosan ni on wa ti egbe Domonu fi yan on ni Alakoso ijoba, ti egbe na si ko on kun egbe Domonu.

Ọgbẹni Omokowajo se alaye pe ko dun mọ on lati dapọ mọ egbe Domonu tele

(Wo oju ewe kejọ)

## Iparun ẹgbẹ onikumọ

O LE ni ẹgbẹdogun enia tile toko Ijebu ti o wa sibi idasile Ẹgbẹ Ọdọ ọmọ ogun Ẹgbẹ Afẹnifẹre Naijiria, "Awo National Pioneers" ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ogunjọ oṣu yi. Nibe gbogbo won fẹnu ko lati gba Awẹ fun ọjọ meje ki ọjọ

(Wo oju ewe kejọ)

## 'Gbogbo Ibadan d'ẹlẹwọn ka'lẹ laiye Ẹgbẹ Akintọla'

